*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

## Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ

nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

# Ǹjẹ́ Ìwọ́ ti Ṣetán?

**Ṣé o ṣì rántí?** Bí a ṣe ń sùn, tí à ń jí ni à ń súnmọ́ òpin àkókò wa lórí ilẹ̀-aiyé. Mọ̀ pẹ̀lú pé, Ọlọ́run lè yàn láti mú ènìyàn rere, ènìyàn burúkú, ọlọ́rọ̀, tálákà, ọmọdé, àti àgbàlagbà kúrò láiyé nígbàkúgbà. Kò sí ẹnìkan tí yóò gbé ilé-aiyé láilái. Olúkúlùkù ló sì ní ibì kan pàtó tí yóò wà, nígbẹ̀yìn. Ní ọdún díẹ̀ sẹ́yìn, arákùnrin kan nínú Krístì sọ fún wa bí iyawo rẹ̀ ṣe wàásù Ìhìnrere sí ọ̀rẹ́ rẹ̀ kan lórí fóònù, tó sì kú lọ́jọ́ kanna. Àwọn ènìyàn ti wà, tí wọ́n jí ní òwúrọ̀ láti lọ sí ibi iṣẹ́ tàbí ibi ìṣòwò wọn, ṣùgbọ́n wọn kò padà sílé. Wọ́n ti di olóògbé! Dájúdájú, púpọ̀ nínú wọn tọrọ fún ẹ̀mí gígùn. Síbẹ̀, òtítọ́

*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ

nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL
~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé

www.divineliterature.org
www.doveletters.org

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

Ǹjẹ́ Ìwọ́ ti Ṣetán?

Ṣé o ṣì rántí? Bí a ṣe ń sùn, tí à ń jí ni à ń súnmọ́ òpin àkókò wa lórí ilẹ̀-aiyé. Mọ̀ pẹ̀lú pé, Ọlọ́run lè yàn láti mú ènìyàn rere, ènìyàn burúkú, ọlọ́rọ̀, tálákà, ọmọdé, àti àgbàlagbà kúrò láiyé nígbàkúgbà. Kò sí ẹnìkan tí yóò gbé ilé-aiyé láilái. Olúkúlùkù ló sì ní ibì kan pàtó tí yóò wà, nígbẹ̀yìn. Ní ọdún díẹ̀ sẹ́yìn, arákùnrin kan nínú Krístì sọ fún wa bí iyawo rẹ̀ ṣe wàásù Ìhìnrere sí ọ̀rẹ́ rẹ̀ kan lórí fóònù, tó sì kú lọ́jọ́ kanna. Àwọn ènìyàn ti wà, tí wọ́n jí ní òwúrọ̀ láti lọ sí ibi iṣẹ́ tàbí ibi ìṣòwò wọn, ṣùgbọ́n wọn kò padà sílé. Wọ́n ti di olóògbé! Dájúdájú, púpọ̀ nínú wọn tọrọ fún ẹ̀mí gígùn. Síbẹ̀, òtítọ́

ibẹ̀ ni pé, wọn kò sí pẹ̀lú wa mọ́. Bí wọ́n ṣe kú, ìdí tí wọ́n ṣe kú, tàbí ìgbà tí wọ́n kú kọ́ ló ṣe pàtàkì, bíkòṣe ibi tí wọ́n wà báyìí. Bí àwọn kan nínú wọn ṣe ń gbé ọjọ́ kọ̀ọ̀kan bíi ọjọ́ tí wọn ó lò gbẹ̀yìn, àwọn òmíràn o múrasílẹ̀ rárá. Ìwọ ńkọ́? Ǹjẹ́ ò ń múrasílẹ̀ bí? Ṣé o ti wà ní ipò ìbátan pẹ̀lú Jésù Krístì?Níbo ni ìwọ́ fẹ́ wà títí aiyéraiyé, lẹ́yìn tí o bá fi aiyé yìí sílẹ̀? Níbo ni o rò nínú ọkàn rẹ, ní ti òtítọ́, pé ìwọ yóò wà?

Gbogbo wa la ní kádàrá láti kú. Lẹ́yìn ikú, ìdájọ́ lókàn (Heberu 9:27). Kò sí ẹlẹ́ṣẹ̀ tí yóò bọ́ lọ́wọ́ ìdájọ́ amúbíiná Ọlọ́run. Pẹ̀lúpẹ̀lú, yàtọ̀ sí ohun tí ọ̀pọ̀ ènìyàn gbàgbọ́, Ọ̀run àti ọ̀run àpáàdì wà, dájú. Ibi ìdùnnú ńláǹlà tí kò lópin ni Ọ̀run (Johannu 14:2-3, Ìwé Ìfihàn 21:1-4). Àmọ́ ibi ìbànújẹ́ tí kò lopin ni ọ̀run àpáàdì jẹ́ (Máàkù 9:43-48) - ibi tí ẹkún àti ìpayínkeke yóò wà (Mátíù 13:41-42)! Ó ṣeni láàánú pé kò sí àyè mọ́ láti wá ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Jésù Krístì lẹ́yìn tí ènìyàn bá ti kú. Yóò ti pẹ́ jù, àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀ yóò sì bá ara wọn ní ọ̀run àpáàdì.

Krístì sọ wípé: *"Èmi ni Ọ̀nà, Òtítọ́, àti Ìyè. Kò sí ẹnikẹ́ni tí ó lè wá sọ́dọ̀ Bàbá, bí kò ṣe nípasẹ̀ Mi"* (Jòhánù 14:6). Èyí túmọ̀ sí pé, ènìyàn wà ní ipò àìní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run, yóò tún kàgbákò wíwà nínú adágún iná tí kò bá sí ní ipò ìbátan pẹ̀lú Krístì, tí ó sì kú bẹ́ẹ̀ (Ìwé Ìfihàn 20:15). Ohun tí ó burú jùlọ tí o lè ṣe sí ara rẹ ni, kí o kú láìjẹ́ pé o jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Krístì. Kì í ṣe ohun tí ó le rárá, bóo ṣe rò, láti jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un. Ṣe ìpinnu láti gba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwà àti Olùgbàlà rẹ; kí o sì ṣe ìpinnu pẹ̀lú, láti máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́. Má ṣe rò ó láti sún Ọjọ̀ Ìgbàlà rẹ síwájú. Àná ti lọ, òní nbẹ fún ọ; ṣùgbọ́n ọ̀lá lè pẹ́ jù!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ́ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*

ibẹ̀ ni pé, wọn kò sí pẹ̀lú wa mọ́. Bí wọ́n ṣe kú, ìdí tí wọ́n ṣe kú, tàbí ìgbà tí wọ́n kú kọ́ ló ṣe pàtàkì, bíkòṣe ibi tí wọ́n wà báyìí. Bí àwọn kan nínú wọn ṣe ń gbé ọjọ́ kọ̀ọ̀kan bíi ọjọ́ tí wọn ó lò gbẹ̀yìn, àwọn òmíràn o múrasílẹ̀ rárá. Ìwọ ńkọ́? Ǹjẹ́ ò ń múrasílẹ̀ bí? Ṣé o ti wà ní ipò ìbátan pẹ̀lú Jésù Krístì? Níbo ni ìwọ́ fẹ́ wà títí aiyéraiyé, lẹ́yìn tí o bá fi aiyé yìí sílẹ̀? Níbo ni o rò nínú ọkàn rẹ, ní ti òtítọ́, pé ìwọ yóò wà?

Gbogbo wa la ní kádàrá láti kú. Lẹ́yìn ikú, ìdájọ́ lókàn (Heberu 9:27). Kò sí ẹlẹ́ṣẹ̀ tí yóò bọ́ lọ́wọ́ ìdájọ́ amúbíiná Ọlọ́run. Pẹ̀lúpẹ̀lú, yàtọ̀ sí ohun tí ọ̀pọ̀ ènìyàn gbàgbọ́, Ọ̀run àti ọ̀run àpáàdì wà, dájú. Ibi ìdùnnú ńláǹlà tí kò lópin ni Ọ̀run (Johannu 14:2-3, Ìwé Ìfihàn 21:1-4). Àmọ́ ibi ìbànújẹ́ tí kò lopin ni ọ̀run àpáàdì jẹ́ (Máàkù 9:43-48) - ibi tí ẹkún àti ìpayínkeke yóò wà (Mátíù 13:41-42)! Ó ṣeni láàánú pé kò sí àyè mọ́ láti wá ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Jésù Krístì lẹ́yìn tí ènìyàn bá ti kú. Yóò ti pẹ́ jù, àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀ yóò sì bá ara wọn ní ọ̀run àpáàdì.

Krístì sọ wípé: *"Èmi ni Ọ̀nà, Òtítọ́, àti Ìyè. Kò sí ẹnikẹ́ni tí ó lè wá sọ́dọ̀ Bàbá, bí kò ṣe nípasẹ̀ Mi"* (Jòhánù 14:6). Èyí túmọ̀ sí pé, ènìyàn wà ní ipò àìní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run, yóò tún kàgbákò wíwà nínú adágún iná tí kò bá sí ní ipò ìbátan pẹ̀lú Krístì, tí ó sì kú bẹ́ẹ̀ (Ìwé Ìfihàn 20:15). Ohun tí ó burú jùlọ tí o lè ṣe sí ara rẹ ni, kí o kú láìjẹ́ pé o jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Krístì. Kì í ṣe ohun tí ó le rárá, bóo ṣe rò, láti jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un. Ṣe ìpinnu láti gba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwà àti Olùgbàlà rẹ; kí o sì ṣe ìpinnu pẹ̀lú, láti máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́. Má ṣe rò ó láti sún Ọjọ̀ Ìgbàlà rẹ síwájú. Àná ti lọ, òní nbẹ fún ọ; ṣùgbọ́n ọ̀lá lè pẹ́ jù!

Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ́ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*